# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO. 539 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 29 — OCTOBER (5) 1962. KỌBỌ MEJI (2D)


ONIGBAGBO WOLE ADURA

# Igun Di Orisa Ni Ilu Ibo

## O Npa Nwon Leran Je

AHOADA—Nwọn ni bi unnugun ba w ilu ara a no rọ awọn ara ilu sowo, a si mọ tun rọ nwọn somọ, ṣugbọn inira ni awọn ogunlọgọ igun ti o ṣeṣe de wọ ilu Ahoada leti Port-Harcourt ko ba awọn ara ilu na t'agba tomọde atoripe gbogbo ewurẹ wọn, aguntan wọn ati ẹdiẹ awọn ara ilu na ni gunnugun ti yo oju wọn je tan pẹlu ifun inu wọn. Onirohin wa ti o fi waya irohin na ranṣẹ si wa lati Port-Harcourt ni abami ni awọn igun na nitori e nwọn yato pupọ si iru awọn igun ti a mba pade ni ilu Hausa l'Oke Ọya; ori wọn pa, agogo-ẹnu wọn gun, o si mu ṣoṣoṣo, iyẹ apa wọn si tobi pupọ-agogo-ẹnu wọn yi ni nwọn fi nṣe ọṣẹ fun awọn ẹran ọsin awọn ara ilu Ahoada.

Wahala awọn gunnugun na pọ tobẹ ti nwọn fi ngbe nkan ọbẹ lori awọn obinrin lọna ọja, eyi si jẹki awọn agba ilu mu ọrọ awọn igun na tọ awọn babalawo lọ; nwọn ti yan etutu ẹbọ ti nwọn yio ru fun wọn. Awọn onigbagbọ ilu paapa ti wọle adura nisisiyi.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital £3,181,000

HEAD OFFICE
82/86, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

DIRECTORS:

SAMUEL LAYIWOLA DUROSARO-Chairman
Managing Director ABDUL AZEEZ OLAYIDE DUROSHOLA-General Manager AYOTUNDE / OLATUNDE OSHINIBI

LONDON OFFICE
15,THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager J. F. Burton.

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegrams Nathaniger; London.
Head Office Representative in London.

E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG
30 Branches Throughout Nigeria Including

IBADAN BENIN-CITY. SAPELE. ABA. KANO. ZARIA. JOS.


Ọlawoyin Wo Gawu:

# Nwon Wa Omo Oba Kano Kuro Nilu

ILỌRIN— Ọrọ bẹhin yọ, akọwe-agba awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) fun Okẹ Ọya, Ọgbẹni J.S. Ọlawọyin, ti o fi igba kan wa ninu ile igbimọ awọn aṣofin ni Ipinlẹ Ijọba Ariwa ti a gbọ wipe o kọwe si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre l'Eko wipe awọn ara ilu on ni ki on kuro ninu ẹgbẹ na, ki on si di ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) ti wọ ẹwu gaawu lọdọ awọn ara ilu rẹ.

Nwọn ni awọn ko ran ni iṣẹ ti o njẹ rara, nwọn ni mo gbọn tan, mọ mọ tan ni o nṣe e. Ọrọ yi mu ki akọwe awọn ẹgbẹ ọmọ Ọffa, Ọgbẹni J. B. Ọlafimihan tete pe ipade pajawiri fun àwọn ẹgbẹ ọmọ Ọffa lati jiroro lori ọrọ Ọgbẹni Lawọyin na.

(Wo yoku loju ewe keji)

# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu oseti mbo.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20)
O dab eni wipe ọsẹ yi yio fọ rere fun ọ, lori ọrọ ara re ati nipa nkan ifẹ.

PISCES (Feb 21–Mar 20)
Ofo ati isọkusọ le jẹ ki ọkan rẹ fa kuro ninu ipinnu rere kan ti o pinnu wipe wa ṣe ṣugbọn a nfọkan tan ọrẹ eni a ṣe ọ ni ire.

ARIES (Mar 21–April 20)
Ọsẹ a nra, a nti ni eleyi je fun ọ ki o si gbidanwo lati ma jade ki o mọ si koko sile.

TAURUS (April 21–May 20)
Wahala nkankan ti o ti ṣe ọ nigbakan ri ti yio ba ọ lọkan jẹ. Ma gba imọran lọdọ enikan nitoripe imọran ti iwọ alara ni yio ṣe ọ ni ire.

GEMINI (May 21–June 21)
Ṣe awọn iṣẹ ti o ko ti pari ati awọn gbese pepepe tio ba wa lọrun rẹ. Ti o ba ti se eleyi wa gbadun ọsẹ yi.

CANCER (Jun 22–July 23)
Ko dara ki o mọ ti ori ero kan bọ si ominran. Iwọ pelu awọn kan ti e ti jọ nṣe ọrẹ tipe a fẹ dẹhin kọ ara yin ninu ọsẹ yi. Ki o ṣọra.

LEO (July 24–Aug 22)
Imọran ti nwọn ba fun ẹ lori ọrọ ara rẹ tabi olufẹ rẹ a ṣe ọ ni anfani.

VIRGO (Aug 23–Sept 23)
Ma fi ilọra ju nkan iyebiye nu fun ara re lọsẹ yi. Ki a mọ dakẹ nigbati ko yẹ ki a dakẹ ni o nko ba ọ.

LIBRA (Sep 24–Oct 23)
Iwọ paapa le ṣe ara rẹ ni ọga bi o ba le kan oju abẹ ni'ko larin awọn ẹgbẹ rẹ.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22)
Nkan ti o ti nnaga si le tẹ ọ lọwọ ninu ọsẹ yi bi o ba tun gbindanwo lati tun naga si i.

SAGITTARIUS (Nov 23–Dec 22)
Ailera enikan ninu awọn ebi rẹ a mu ọ lẹkan pupọ.

CAPRISCORN (Dec 23– Jan 21)
Ma ti ṣe ipinnu pataki kan a fi ti o ba ri daju wipe nkan ti o fẹ ṣe ipinnu na si o ti ri dajudaju. Ire wa ni ita fun ọ.

# Akanbi Eko Se Ikomo

EKO — Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kerindilogun oṣu yi ni Ọgbẹni Akanbi (Eko) Abisogun ṣe ikomọ ọmọ ti Ọlọrun fi ta on ati iyawo rẹ Anotu Esu lọre ninu oṣu yi. Ni ile wọn ni Idunsagbe ni nwọn ti ṣe aseye ikomọjade na. Nwọn si sọ ọmọ na ni Tawakalitu Iyabode.

Awọn enia pọ bi omi; awọn ẹgbọn baba ọmọ tuntun na, awọn Raliatu Adukẹ ati Nuuratu Alakẹ na wabi-wọsi owo lọjọ na. Baba ọmọ paapa fi nkan jijẹ ati nkan mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa si ibi ikomọ na lọrun. Ikomọ ọjọ na kamọmọ, bi awọn onilu ti nlu ni olukuluku nfi ijo bọ ẹ.

Die ti a le daruko ninu awọn ti o wa si ibi ikomọjado na ni Ọgbẹni Yekini Dawodu, W. Bisiolu, Taoridi Tiamiyuu R. Adegoke, S. Sadiku, Nuru Adisa, K. Oyebọla, Y. Adisa, N. Apatira, O. Ramọnu, B. Ọlayiwọla, T.A. Etiko, O. Ọnatade, Adetunji Oloye, Timothy Olusọla, Yẹkini Alao Lamidi Iyanda, Lasisi Aiki, A. A.Ricca, Karimu Korọkọ, Ọlarewaju Dawodu, A. Raufu Yesufu, Jinadu Ọladipọ, Kayọde Ade, Iyafin Tayibatu Esu Afusatu Adunni, Adiatu Abisogun, Asiata Abike, Abẹbi Abisogun, Nimọta Aṣabi, Abẹgbẹ Eko. Nimọta Abẹbi ati Raliatu.

Oluwa ki o da ọmọ na si.

# Egbe Olomi

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

GBARA ti awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) eka Ilọrin ti gbọ ọrọ yi ni nwọn ti bu ẹtẹ lu ọrọ Ọgbẹni Ọlawọyin na ti o ni on yio di ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ wọn. Nwọn ni ṣe igbayi ni owurọ fun.

Awọn ogunna gbongbo ọmọ ẹgbẹ na ti o wa ni Kaduna ti te waya si awọn ti Ilọrin wipe ki nwọn fa iwe rẹ ya; nwọn ni eru awọn ọlọpa ni o mba Ọgbẹni Ọlawọyin nitoripe ọrọ ti bẹhin yọ si i lori rukerudo ti o bẹ silẹ ni Ibadan.

## Omo Oba Kano Di Eleha

Irohin pataki ti onirohin wa tun fi ranṣẹ si wa lati ilu Kano ni ti ọmọ ọba Kano, Alhaji Ado Sanusi, Alaga ibiṣẹ ti nwọn ti nta ọja si ilu okere (Marketing Board) ti nwọn ni ki nwọn wa kuro nilu Kano nitori iwadi Enkuari ti nwọn nṣe lori bi awọn Ijọba bile baba rẹ ti nse nnawo si.

Nwọn tun rọ loye ọmọ Ọba ti nwọn fi jẹ ti nwọn npe ni Dan Iya. Oye yi si jẹ pataki larin awọn ọmọ Ọba. Onirohin wa fi ye wa wipe nigbati nwọn lọ ba ọmọ ọba yi ni ìwe wipe ko kuro ni ilu, ninu faaji ni nwọn ba a, on ati awọn amugbalẹhin rẹ.

Ko sọ nkankan ju "Allah de" lọ. Onirohin wa ni on gbọ wipe ile kan ni Ikoyi ni nwọn wa lọ l'Eko.

Ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (N P C) ti da si meji ni ilu Kano ati igberiko ilu na. Ni igberiko kan ti nwọn npe ni Bichi nwọn ni awọn ko tilẹ fẹ gbọ orukọ ẹgbẹ NPC na lọdọ awọn mọ.

Advt. NO. 151

**Se o ti lo paro owo atijo owo re**

SI OWO TUNTUN ti ile Nigeria ? O le parọ OWO PEPA korensi L'OFẸ TITI DI IPARI OṢU SEPTEMBER

Ti a wa ninu re yi.

**Ti owo sile ati awon isongbe re di ipari osu**

DECEMBER.

## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

PUBLIC NOTICE

INDEPENDENCE ANNIVERSARY CELEBRATIONS
CLOSURE OF PORTS

It is hereby notified for general information that ALL PORTS will be closed on Monday, 1st October, 1962, being a Public Holiday and that no port operations will take place on that day.

L. ADE. KUYINU
for: Secretary to the Authority

N.P.A. NOTICE NO. 769.
24th September, 1962.

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (3)

## (Lati Owo Omo Abati)

### Adetokunbo

Nigbati Ọba Gbadebo pẹlu ọmọ ẹgbọn rẹ, ọmọ'ba Ladapọ (orukọ ti gbogbo awọn ọmọ Ẹgba asiko igba na mọ Alaiyeluwa Ọba wa si ni yẹn nigbana) ti ilu Oyinbo de, ọpọlọpọ awọn nkan meremere ti nwọn ri, ti awọn Oyinbo ṣe si ilu wọn ni awọn na si gbero lọkan wọn wipe awọn ni lati ṣe si ilu Ẹgba fun anfani awọn ara ilu. Nwọn si fi gbogbo rẹ si ero.

Gbara ti Ọba wa yi ti pada de lati ilu Oyinbo, iyawo rẹ ọmọ Alakija ti o ti fi sinu oyun ti bi ọmọkunrin kan jojolo. Nwọn si sọ ọmọ na ni ADETOKUNBỌ, ọmọ na si ni ọlọla wa, babasalẹ awọn Adajọ Kotu-nla ti ẹ mọ orukọ rẹ ni Sir Adetokunbọ Ademọla loni. On ni o si nṣe olori gbogbo awọn adajọ-agba ni gbogbo ilẹ Nigeria lori.

### Omi-Ero

Boya ẹnyin ti o nka itan mi le gbọ wipe laipe yi ni nwọn tun ṣi ile-ẹrọ omi kan si ilu Abẹokuta; bẹni. Lẹhin Eko, ko si ilu ti o kọ lo omi-ẹrọ ju Abẹokuta lọ ni gbogbo Nigeria. Ijọba Gẹsi ti o wa l'Eko ni o ṣe onfa omi-ẹrọ si ilu Eko nigbana, ko si ju ọdun keji lọ nigbana ti aroja ẹrọ-omi awọn ti Ẹgba paapa fi de.

Awọn alakoso Ijọba Ẹgba ni ile-iṣẹ ti nwọn nibiti awọn gbe ti nṣe iṣẹ ala oju-ọna (PWD); nwọn si gba awọn Oyinbo ti o mọ oju-ọna la ati awọn ti nwọn mọ afara kọ si ibi iṣẹ wọn na.

### Kekeye

Eyiti o jẹ pataki ninu awọn oju ọna-titi ati afara ti nwọn kọ mojuto ni oju ọna-titi ti o la arin ilu bi ọna Ibara mọ ọja Ṣapọn lọ si Ake nitoripe Ibara ni ọkọ Reluwe kọ gbe pin si nigbana, nwọn si npe Tesan Ibara na ni Tesan Abẹokuta; ọko Reluwe ko ti de Lafẹnwa nigbati awọn Ọba wa ko lọ si ilu Oyinbo ni iwọn nkan bi ọdun mejidi-logota (1904) sẹhin.

Ilu ti oke pọ nibẹ pupọ ni ilu Abẹokuta. Oyinbo kan ti o jẹ pataki ninu awọn ti o ṣe iṣẹ oju-titi na nigbana ni ọkan ti awọn Ẹgba sọ ni KEKEYE. Orukọ ti iya ati baba rẹ ko sọ o.

Awọn Ẹgba fun Oyinbo na ni orukọ yi nitoripe o jẹ enia kukuru, ara rẹ si fẹr; nilẹ o si fẹran a nwọ ṣokoto penpe (Knicker) fun iṣẹ ode ti o nṣe; awọn ti Ẹgba si ni ọti Oyinbo (Schnapp) kan ti igo rẹ kere ti nwọn ma nmu nigbana ti nwọn npe ni KEKEYE, nwọn si fun Oyinbo ala-oju-ọna yi ni orukọ yi, orukọ na si mọ ọ lori pupọ.

### Ago-Oba

Gẹgẹbi mo ti sọ fun nyin ninu iwe itan mi yi wipe ilu oloke ni Abẹokuta ilu Ẹgba; adugbo kan wa ni ibẹ ti nwọn npe ni Oke Ago-Ọba; Oyinbo ti nwọn sọ ni KEKEYE yi si jẹ pataki ninu awọn ti o la oju ọna titi gba Oke Ago Ọba titi o fi fori sọ odo Ogun ni Lafẹnwa ki nwọn to kọ afara (Bridge) sibẹ.

Awọn ara adugbo Ago-Ọba yi jẹ awọn ti nwọn nṣe ngbe orisi wọn jade lododun, ṣugbọn ni nọdun ti nwọn la oju ọna titi gba igbo agẹmọ wọn, awọn alagẹmọ ko ri igbo igbalẹ lati mu agẹmọ wọn jade, ni awọn ara Abẹokuta ba fi nwọn kọrin bayi:-

"Kekeye lo wole Agẹmọ,
Kekeye lo wole Agẹmọ,
Ara Ọba mi s'ọdun ko r'Agẹmọ.
Kekeye lo wole Agẹmọ.
Kekeye ! Kekeye !!
Abi ṣokoto kọ bi akukọ."

### Lebira

Nitoto, awọn oṣiṣẹ Oyinbo Kekeye yi si Oke Ago-Ọba dilẹ; ni igbana ko si aiye a nfi ẹrọ gbẹ ilẹ, kosi iru ẹro to nla oju-titi ni kiakia ti ẹ npe ni Katapila laiye isiasiyi. Agbara awọn ọmọ enia, ti nwọn npe wọn ni lebira ni nwọn nlo.

Gbogbo igba ti mo itan nipa rẹ yi Ọba wa, Alaiyeluwa Ladapọ Ademọla keji yi si wa ni ilu Eko ton nṣe Aṣoju fun Ijọba ilu Ẹgba ti o wa ninu Oṣinṣinra nigbana,

Ti o ba di ọsẹ ti mbọ ma sọ diẹ fun nyin nipa awọn gbajumọ ti o mba rin nigbati o wa ni ilu Eko na.

(Koi ti pari)

Advt. NO. 134

NOTICE

NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions :-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries.

(ii) Do you consider that such awards should take form of :-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-
The Secretary
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962.

# Duro De Asiko Oluwa

## (Lati owo Latifu Babalola)

Nigba lailai, ẹyẹ kan wa, nwọn npe ẹiyẹ na ni Gunugun; ẹiyẹ yi pẹlu Aṣa a ma ṣe ọrẹ pọ, wọn a si ma lọ si ile ara wọn. Gẹgẹbi gbogbo yin ti mọ pe Adiẹ ni aṣa nia npajẹ, ati wipe ẹbọ ati oku enia ni Gunugun ma nwo pa jẹ kiri on ki jẹ ole rara.

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

# ELETI-OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosọko Street, Lagos. P. O. Box 468 — "ELETI OFE," LAGOS Phone 23370.

VOL XIV. No. 839. SATURDAY SEPT. 29, - OCT. 5, 1962


# E Fi Eyi K'ogbon

NI ọsẹ ti o kọja yi ẹnyin ọkawe wa niran ọrọ ti a fi ṣe olori ọrọ wa nipa alejo pataki kan, Alakoso Ijọba ilu India, Ọgbẹni NEHRU ti a gba ni alejo ni ilẹ yi. Alejo wa na sọrọ kan fun awọn oṣelu wa ninu ile Igbimọ awọn Aṣofin ti o jẹ ọrọ atata ti a fẹ ki ẹnyin ara ilu yi fi kọ ọgbọn.

Ọgbẹni NEHRU ni ẹnikẹni ti nwọn ba fi ida alaṣẹ Ijọba le lọwọ o yẹ ki o lo aṣẹ na ni ọna ti yio fi jẹ irọrun fun gbogbo ara ilu na.

### Mekunnu

O ni bayi ni a nṣe ni ile wa, ewọ si ni ninu ile miran: o ni nkan ti o ndamu gbogbo araiye lode oni ni "ohun ti ẹgbẹ mi ṣe nkan saiṣe e" Sugbọn gbogbo wa ti gbagbe awọn mẹkunnu ilu. Bi a ko ba si fi ti awọn mẹkunnu yi sero nkan ko le toro fun awọn oṣelu nitoripe ẹmi awọn oṣelu ni mẹkunnu.

Nitotọ ni ọrọ Ọgbẹni Nehru yi, oni kọ si ni awa onirohin Eleti-Ọfẹ ti nṣe ikilọ fun awọn oṣelu wa, awọn Minisita wa ati awọn akọwe ibi iṣẹ Ijọba wa wipe ki nwọn ye ko iyan awọn mẹkunnu ilu kere ti nwọn ba fẹ ki ilu ko toro ki gbogbo wa le ni alafia.

Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi, bi o ba de inu rẹ a di odidi.

## AIROJU BA ILU GHANA

ACCRA—Airoju airaye ti ba gbogbo awọn ọmọ Aganyin ni ilu Ghana nitori ofin ki onile gbe il ti awọn Alakoso ilu na gbe jade laipẹ yi nitori bọmbu oloro ti o tun bu ni aipẹ yi ti o pa ọpọlọpọ enia nibiti nwọn ṛe pejọ si lati ba Dokita Nkrumah yọ ayọ ọjọ'bi rẹ. Dokita Nkrumah alara paapa ko le jade ba wọn yọ ayọ na kakiri arin ilu.

Lati ibẹrẹ ọsẹ yi gbogbo mọto bọlẹkaja ti o fẹ mu nkan onjẹ wọ ilu ni awọn ṣọja ati ọlọpa nda pada ti nwọn si nyẹ gbogbo awọn ero inu ọkọ na wo, awọn ni ẹniti kò ba gba iwe aṣẹ ko gbọdọ wọ ilu Accra.

Ọrọ airoju ti o ba wọn ni ilu Aganyin yi ni ko jẹ ki Alakoso Ijọba ilu India, Ọgbẹni Shri Jawaharlal Nehru lọ ba wọn ni alejo ni ilu Ghana na mọ. Lẹhin ti Ọlọla Alakoso na ti pari ibẹwo lọdọ wa tan, ilu rẹ lo doriko. O ni on ko le gba iku oriku ku.

# Iwe Si Olotu

# Itan Alake Dun Ninu Eleti-Ofe

Emi gẹgẹbi olukọ ile iwe kan ni ibi gbadun itan Alaiyeluwa Ọba Alake Ademọla Keji ti asọtan kan, Ọmọ Abati nsọ ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ lati ijọ kedogun osu yi.

Ni ilu Abẹokuta ni emi paapa ṣe ọmọde ti mo si lọ si ile ẹkọ ki nto jade lati maṣe iṣẹ olukọni sugbọn nko mọ nkan na to bi opitan yi ti sọ ni ẹkunrẹrẹ to yi.

Iru awọn itan atijọ bayi ti a nri ka ninu iwe Eleti-Ọfẹ ni o njẹ ki a mọ gbadun iwe irohin na yatọ si awọn miran.

Olotu, mo ti fi awọn iwe Eleti-Ofẹ yi pamọ fun awọn aromọdọmọ mi, ki awọn le ri nkan itan ka lẹhin ọla.

Ẹ ṣe pupọ, ki ẹ tun tẹ omiran fun wa.

Emi ni,
Ita Iyalode, Tiṣa
Ikorodu


# E polowo oja yin si iwe Eleti-Ofe


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

ELECTION OF MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF SHIPS' DUES AND THE PAYERS OF HARBOUR DUES HELD ON THE 21st day OF SEPTEMBER, 1962.

NOTICE IS HEREBY GIVEN that in accordance with the provisions of the Nigarian Ports Authority (Election) Regulations 1956 the under-mentioned candidates have this day been duly elected as Members of the Authority to represent the payers of Ships' Dues and the payers of Harbour Dues with effect from 23rd September, 1962.

MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF SHIPS' DUES:

Chief Kolawole Balogun
Chief Shafi Lawal Edu
William Jesson Joyce, Esq.

MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF HARBOUR DUES:

David Fleming, Esq.
William Geoffrey Duncan, Esq.
Alhaji Shittu Ade. Fashola.

L. ADE. KUYINU
Returning Officer

21st September, 1962.
N.P.A. Notice No. 768.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI OWO AYILUKA)

## Ona Orun

Nwọn ni bi ojugba ẹni ba nku ominu a mọ koni Odu Ifa kan ti o ni: "Mo pe oniboce aiye o da mi lohun lọna jinjin tian-tian; mo pe Onibode ọrun, o da mi lohun nitosi nitosi, njẹ Ọrunmila ni ẹnikẹni ti o ba ni ohun didun ki o mọ jẹ, ona ọrun ko jina, ẹniti o ba ni ohun didun ki o mọ jẹ, ọna orun ko jinna" ni o yẹ ki nfi tu ọfọ ọrẹ mi kan, ọdọmọde ti nwọn npe ni L. A. B. Marquis, ọmọ Aguda ti o jalaisi ninu ọsẹ yi.

## Ko Jina

Nitotọ, ọna ọrun ko jinna. Ọmọ ọdun merindinla-dọta ni arakunrin na, iṣẹ dokita jigi-oju ni o nṣe leti Mọsalasi Jimọ l'Eko. Ko ro iku si ara rẹ ni ijeje ọjọ Aiku (Sunday) ni on mura ti o lo ba wọn ṣe aṣeye nile Gomina-agba; eleyi si ni odẹ ti o lọ gbẹhin ki o to lọ si Alukiyamọ.

Mo ki Tunji, ọmọ rẹ ati iyawo rẹ, ọmọ Lọya Fereira, pe nwọn ku aṣẹhinde. Olodumare ma jẹ ki a ri iku ojiji mọ. Ọlọrun ma jẹ ki a ri abiku agba. Adisa, ọrun re.

## Airoju Ni Ghana

Boya ẹnyin ọkawe mi le sọ wipe, "ipakọ onipakọ ni a nri ẹni-ẹlẹni ni o nri ti wa," ni ọrọ awọn ara ilu Ghana ti mo fẹ fi ẹnu ba ninu iwe irohin "wosika" mi ninu ọsẹ yi; bẹni.

Nitotọ, ilu Nigeria koi ti toro lọwọ-lọwọ nisisiyi bẹni ile ni a ti nko ẹsọ lọ si ode. Kini faa? Ọpọlọpọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin ti nio mba pade ni alai ko ni ifẹ larin ara wa ni o fa gbogbo rogbodiyan na. Awọn Yoruba ni bi awọn kan ba nti oko-were bọ, awọn kan a ma lẹ. Bẹni ọrọ ilu Nigeria ri nisisiyi lọdọ awọn Aganyin.

## Airaye Najiria

Were ti awọn kan ti gbo koran-koran, awọn kan ṣẹṣẹ fẹ bẹrẹ ti wọn. Nwọn ni iwa airoju ni o ba wọn ni ilu Aganyin (Ghana) ṣugbọn ọrọ airoju ati airaye lo ba gbogbo ilẹ yi ni Ipinlẹ Ariwa, Ila Orun ati Iwọ Orun. Ibiti gbogbo rẹ yio gunlẹ si ko si ẹniti o le sọ.

## Itimole Ko Ko Enikan

Ọrẹ mi kan njẹ oriki kan, o ni on "Itimọle ko kọ ẹnikan ;" ẹlẹha apapandode ni a ti nwi ri. Itimọle ọsan gangan yi ko ye enia. Ọsẹ buruku ni ọsẹ ti o nlọ yi jẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ ọlọpẹ ti a npe ni ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) nitoripe o ti di mẹfa ninu awọn ogunna gbongbo ọmọ ẹgbẹ na ti Dokita Koye Majẹkodunmi, Adele Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, ti ni ki awọn ọlọpa ko lọ pamọ si Ọgba ẹwọn.

## Awolowo Nlo Kano ?

Lẹhinti nwọn ti mu awọn bi Ogbeni Bisi Ọnabanjọ ("Aiyekotọ"), Lati Jakande ("John West"), S. T. Ọrẹdẹin, Lọya M. A. Omisade ati Ayọ Akinsanya lọ pamọ si ọgba ẹwọn, mo gbọ wipe ilu Kano ni nwọn fẹ ru Oloye Awolọwọ lọ. Nwọn fẹ ṣe ọrọ tiẹ ni oke Ebute-Mẹtta ko ṣe sare de.

Ẹrẹkẹ ọlọkanrun, a wu ki o to bẹ, nitoripe mo gbọ wipe o tun ku ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn tun fẹ ha iwe ile-ẹwọn fun.

Ọrọ re o, ẹnyin ara Nigeria !


**NIGERIAN PORTS AUTHORITY**

NOTICE OF INVITATION TO TENDER

CONSTRUCTION OF SENIOR AND JUNIOR SERVICE QUARTERS AND VARIOUS SITE WORKS AT BONNY-EASTERN REGION

The Authority announces its intention to invite tenders for the following works at Bonny:-

SITE A - The construction of four quarters for use by Senior Service personnel, Generator house, Stewards and tradesmen's quarters; various site works including reclamation of part of the site, concerete road; water supply reticulation system; sewers and septic tank; pathways, perimeter fence and surface water drains.

Site B - The construction of seven blocks of quarters for use by Junior Service personnel; five blocks of toilets (bucket type) various site works including reclamation.

Contractors who have the requisite experience, staff and plant to undertake these works are invited to apply to the Authority's Chief Engineer to be included in the list of those invited to tender. The application should be supported by evidence of the required experience, staff, plant and financial background. The Authority reserves the right to select a short list of Contractors to be invited to tender and will not enter into correspondence with any applicant not selected.

The closing date for application will be October 12th, 1962.

L. A. KUYINU
Ag. Secretary to the Authority.

N.P.A. NOTICE NO. 770.
25th September, 1962.



# E ka

**Iwe irohin Eleti-Ofe**

**Ki e si ma polowo oja yin sinu re.**

## Zumratul Ilujaj Se Ase Ojo Ibi Anobi

Irohin ko to afojuba ni ase aladun repetẹ ti ẹ g b ẹ Zumratul H u j a j Niger a ṣe ni alẹ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu k ẹ s a n ọdun yi fun ajoyọ ọjọ-ibi Anabi Mchanmed (Ki ikẹ ati ọla mọ ba a titi lailai) Orişirişi onjẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ na pese gọbọi si i l e onje atata (Palace Hotel ) l'eti O k u n l'Eko; Ọlọla Ọ b a Adenji Adele si ni alaga ijoko ọjọ na.

Ẹsẹ awọn alaji ati awọn minista, a w ọ n bi Alhaji ọlọla Nuhu Bamali, Alhaji Yaya Erubo (Ilọrin) A. R. Laguda, Y. Ayinla Disu, A l h a d j i B. T. Shekoni, Alhaja H. M. Shodchinde ati Alhaji ọ k ọ rẹ, Alhaji Owokoniran, A l h a d j i Iman Agba Olọje Liadi Ibrahim, A l h a d j i-olori Bashirudeen Jaji, nwọn le ni igba enia.

Gbogbo awọn ti o sọrọ lojọ na, awọn bi ọba Adele keji, Alhaja H. M. Shodehinde M. B. E. ati Alhadji Ọlọla Nuhu Bainali (Minista Alabojuto a w ọ n ilu okere) ati Alhaji A. F. Masha sọ ọrọ apọnle pupọ nipa Anọbi Muhanmed (ki ikẹ ati ọla ma ba titi lailai, Alhaji Iman Agba Liadi Ibrahim si fi adura mu ase na wa si ipari.

Nwọn si ṣe sinimọ nipa awọn ti o wa ni ilu mimọ Mẹka a t i awọn i l u ti o wa ni agbegbe rẹ.

## Duro De Asiko Oluwa

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Lasiko kan, iyan nla kan mu ninu ilu, nwọn ko gbe ẹbọ s i t a mọ nitoripe awọn ara ilu paapa ko ri nkankan jẹ depo ti nwọn yio fi rubọ eyi si jẹ ki ebi ma pa Gunugun ati awọn ọmọ rẹ tobẹ ti nwọn fi ru ti nwọn si nkako si ori igi kan ti nwọn npe ni apa.

Ni ọjọ kan, Aṣa dide lati ile rẹ, o lọ ki ọrẹ rẹ gunugun nigbati ko ri ifun jẹ fun o d i d i ọjọ mẹjọ, ni-bati Aṣa yio de ọdọ rẹ, o ba gunugun nibiti o kajọ si, o si bi lere pe kini ṣe ti iwọ ọrẹ mi fi kajọ bayi? Gunugun si da a lohun pe o ti to ọjọ mẹta ti ebi ti npa on ati awọn ọmọ on, nitori iyan ti o mu ko jẹ ki nwọn tun gbe ẹbọ s'ita mọ.

Aṣa wa bere lọwọ gunugun wipe e ṣe ti iwọ ko fi gbe ọkan lara awọn a d i ẹ to nrin kakiri nwọnyi?

Gunugun si da a lohun wipe o ṣe pupọ, bi on ba lọ gbe ọkan ninu won, Ọlọrun yio binu si on nitori Oluwa sọ ninu iwe mimọ pe "Iwọ ko gbọdọ ja olẹ." Aṣa si dahun wipe nibo ni iwọ yio ti ri onjẹ jẹ? Gunugun da lohun bayi, "emi yio duro de asiko Ọlọrun." Nigbana ni aṣa kigbe wipe ha! aṣe olori omugọ paapa ni ọ, nigbawo ni iwọ mọ, ti asiko Ọlọrun yio de, ti ebi ko fi ni pa ọ ku,? "Emi ni temi, mo ma ti pa adiẹ kan jẹ ni owur ọ yi, Ọlọrun Olodumare ko ma ti tori iyẹn binu si mi rara. Bi o ba jẹ bi irọ,

(Wo yoku loju ewe kejọ)

IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200

DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO

DINKU PUPOPUPO –

O NMU MOTO—WIWA RORUN PELU AISI EWU !



Mọto Austin to lagbara yi lanbọ nṣe alekun wiwa mọto laisi ewu nitoripe a ti ṣe e dara tobẹ, eyiti yio jeki iṣẹ rẹ yafafa, owaju si i, ki ere si ma wọle pupọ fun ọ. Mọto S ati T 200 ni mu fifẹ, to si balẹ fun ẹru kiko; jiji iwaju rẹ lagbara, o si njẹki ewu ma dada: ẹjulẹrọse rẹ njẹki moto ṣe wa fẹhinrin laisi ewu. Bere pe ki a wa a wo ki o ri i.

AUSTIN
S 200

SCOA Motors

Nigeria Head Office 257 — 241 Igbosere Road, Private Mail Bag 2085, Lagos. Garages at Aba, Apapa, Benin, Ebute, Ibadan, Jos, Kano, Lagos, Onitsha and Port Harcourt.

# Lecture On "Gari" In London

## Nigerian Expert Addresses Food Congress

LONDON Fourteen hundred food experts from over 40 countries attending the first International Congress on Food Science and Technology in London, recently heard a paper on "The Manufacture Of Gari" given by a Nigerian scientist.

He is Mr. I. A. Akinrele, M. A. (Cantab), D.I.C. of the Federal Institute of Industrial Research at Ikeja, with Mr. R. A. Holgate also of the Institute, he is representing Nigeria at the conference which is discussing how international co-operation in food science can help to feed the world's hungry.

"It is proving a most worth while and well-timed congress, particlarly in the field of shaping policies how to develop our own food resoursces, both agricultural and processing," said Mr. Akinrele.

"Some of the Indian delegates who have been developing ways of producing traditional foods in large scale food processing factories, have expressed great interest in my paper describing our own investigations into developing a mechanical system producing gari."

During the week before the congress, Mr. Akinrele visited research institutions in many parts of Britain to see some of the latest developments since his student days at Cambridge.

### British Developments

"A visit to Torry research station at Aberdeen proved particuly rewarding," he commented in connection with launching a Nigerian stockfish industry. "They have begun work on trying to develop a heat dryer for fish, using the flue gases in trawlers, which is something we have been trying to do at the institute."

Mr. Akinrele explained that freezing methods would be too costly whereas heat drying at sea would provide Nigeria with a traditional dish from plentiful home resources.

"We should prefer to buy a heat dryer and adapt it, so the Torry experiments could be of the greatest help to us," he said.

Another subject of great importance to Nigeria was the production of protein from vegetables which Mr Akinrele saw at Rothamsted Research Centre in Hertfordshire.

"Now that I have seen the advanced work at Rothamsted I am more than ever convinced that out vegetation could provide enough protein for all our population," Mr. Akinrele declared.

Next week he is going back to Cambridge to study the development in the low temperature research laboratory.




# British Exports Are Growing Rapidly

### KEY WORD IS "BUY BRITISH" GOODS

LONDON—"Export trade in Great Britain is growing rapidly," says a London Press Representative. The growth of British exports to Western Europe, which has been a feature of Britain's trade in the last few years, has continued during recent months. Board of Trade figures issued yesterday showed that in the three months, June August export to Western Europe increased by 4 per cent. over those in March–May, including an 8 per cent increase in exports to Common Market countries.

## Duro De Asika Oluwa

(O bere loju ewe kefa)

Iwọ wo mi, loju rẹ korokoro yi ni ngo lọ gbe adiẹ ti on tan ile jẹ lọhun ni, ngo lọ fi pata bẹni Ọlọrun ko ni binu si mi.

Asamọsamọ, aṣa yi ko mọ rara wipe igi kan mbẹ nibiti adiẹ na ngbe tan ile jẹ to mu lẹnu so soro, ti o si gun bi iṣo ẹsẹ bata kan. Bi aṣa ti gbera pa ti o fẹ lọ pa adiẹ na, ni o ba fi igba aya rẹ gun igi na, igi na si wọ inu rẹ debi ti o fi yọ lodi keji ti ifun inu rẹ fi tu jade lojiji o bẹrẹ si ja piti-piti—ija oro iku.

Bẹni gunnugun rọra, o nwo o, nigbati ọrọ na ṣẹ nde oju iku fun aṣa, gunnugun gbera lati ori igi ti o wa pẹlu irora ebi lati lọ wo on ti o ṣe aṣa ti ko fi gbe adiẹ na mọ. Nigbati gunnugun de bẹ, o ri ti gbogbo ifun aṣa ti da silẹ, gunnugun si pe ọmọ rẹ wipe ki o ma bọ, oniẹ de'lẹ, awọn mejeji si bẹrẹ si jẹ ifun aṣa, aṣa ti ko ti ku tan si nkigbe wipe ye! ye!! ifun mi ni ẹ nfa yi; gunnugun si dahun pe agbedọ, ẹjọ on kọ, asiko Oluwa ti mo nsọ fun ọ, ti iwọ ko gbagbọ lo de fun emi loni yi Bayi ni gunnugun ati ọmọ rẹ bẹrẹsi jẹ ifun aṣa ni ajẹyo bamubamu.

Itan yi kọ wa pe ki a ma duro de asiko Oluwa ninu ipokipo ti a ba wa.

## Eka Iwe Irohin Eleti–Ofe



Facts speak for the selves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last, just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA.

SUB—DISTRIBUTORS:

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 26 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE 15, Kosoko St., Lagos,